## "A GBẸ ỌGBUN NLA KAN SI AGBEDEMEJI"
## Luku 16:19-31

Jesu Kristi Oluwa sọ itan kan ti o kun fun ironu, nipa awọn ọkunrin meji ti nwọn yatọ si ara pupọpupọ. Ẹni ekini jẹ ọlọrọ pupọ, ẹni ekeji si jẹ talaka ati. Ọlọrọ yi ko tilẹ ni isoro kankan ninu aiye yi, a maa wọ aṣọ ala a si maa jẹ onjẹ aladun, ni akotan o ngbe ninu irọra ati faaji. Talaka alagbe yi ko ri ọnje jẹ kọja awọn ajẹku onjẹ ẹlomiran, aṣọ akisa ni o si maa nwọ, bakanna ni gbogbo ara rẹ si kun fun ooju ati-egbo kikẹ.

Ṣugbọn, lojiji ni ibi iṣẹlẹ yi yipada. Awọn ọkunrin mejeeji ku, Jesu Kristi si si ferese aiyeraiye han wa. O si se apejuwe iru ayida ti o banilẹru ti o sẹlẹ si wọn. Ọlọrọ nisisiyi wa ninu irora ati iṣẹ oro. Ạlagbe yi, Lasaru wa ninu ayọ, alafia ati isimi. Nigbati ọlọrọ ri Lasaru, o bẹbẹ wipe ki Lasaru wa tọ ikan omi kan si on li ẹnu lati le tu u lara ninu iṣẹ oro rẹ. A ko gba eleyi fun u pẹlu alaye wipe: "a gbẹ ọgbun nla kan si agbedemeji" wọn. Ohun ti Jesu Kristi nfẹ ki o ye wa ni wipe Ọlọrun ti gbe alafo tabi ọgbun kan ti o tobi, ti ko ṣe yipada ti ko si se rekọja si aarin awọn ẹniti a ti gbala ati awọn ti o sọnu ninu aiyeraiye.

Bi enia ba ka iwe yi laironu jinlẹ daada, ero ti yio wa si enia lọkan ni wipe: jijẹ ọlọrọ ati jijẹ talaka ni ohun ti Jesu fẹ mu jade ninu itan yi. Ṣugbọn nigbati a ba fi oju inu wo itan naa, awa yio ri wipe, ọkunrin ọlọrọ yi ti fi ọrọ se igbẹkẹle rẹ, nitori idi eyi, ko ri aye ronu nipa Ọlọrun mọ rara. Ni awọn ẹsẹ 29 titi de 31, a

o ri wipe ohun ti Jesu nsọrọ le lori gan ni gbigbọ ọrọ Ọlọrun, ati yiyipada pẹlu ironupiwada. Njẹ ohunkohun ha wa ninu igbesi aiye rẹ ti ko ni jẹ ki o ni ironu Ọlọrun ninu ọkan rẹ bi? Bi o ba jẹ bẹẹ, Jesu Kristi mu ki o da ọ loju nisisiyi wipe ninu aiye yi nikan ni o ti ni anfaani lati ronu mọ. Lẹhin iku, gbogbo aiyeraiye ni iwọ yio ni lati fi ronu nipa rẹ, ṣugbọn, o se, O TI PẸ JU, iwọ ko le ṣe ohunkohun lori rẹ mọ. Ọgbun nla ti a gbe kalẹ yi nsọ fun ọ nipa ti iyapa aiyeraiye kuro lọdọ ohun gbogbo ti o jẹ mimọ, didan ati daradara.

Nitori awọn idi wọnyi, duro fun iṣeju diẹ, ki o si bi ara rẹ leere, iha ibo ni iwọ yio wa nibi ọgbun naa, nigbati iwọ ba fi ori ilẹ aiye yi silẹ. Ranti wipe bi iwọ ko ba si ni iha ti Oluwa nisisiyi ni aiye yi, iwọ ko le wa ni iha Rẹ ni ọjọ naa.

Bi igbala rẹ ko ba ti da ọ loju, maṣe fi ohun ti o se pataki bi eleyi jafara, mase sọ di igba miran. Ọrọ Ọlọrun sọ wipe: "Nisisiyi ni akoko itẹwọgba, Kiyesii, nisisiyi ni ọjọ igbala" (2 Korinti 6:2). "Ma ṣe ileri ara rẹ niti ọjọ ọla, nitoriti iwọ ko mọ ohun ti ọjọ kan yio hu jade" (Owe 27:1).

Oluwa Jesu Kristi nduro lati dariji gbogbo awọn ti yio tọ Ọ wa pẹlu ọkan ironupiwada, ti yio si tẹwọgba ẹbun igbala iyebiye Rẹ, eyiti O ti se ni asepe nigbati O ku fun wa lori igi agbelebu ni Kalfari. Jẹ ọlọgbọn ki o si gba ipe ifẹ yi nisisiyi, ki iwọ ba le ni ipa ninu Rẹ ni ẹkunrẹrẹ ayọ lati le maa yin I ninu aiyeraiye.

**Word Of Truth**, P.O. Box 1126, Kaduna, Nigeria